UK Health Security Agency

NHS

Daabobo ara rẹ tako

# kọọli ati aarun inu ẹjẹ

## Pẹlu abẹrẹ ajẹsara MenACWY



immunisation
the safest way to protect your health

# Kòkòrò Ààrùn Kọ́ọ́lí

**Aarun Meningococcal ko wọpọ sugbọn o le o si nilo itọju ile-iwosan ni kiakia. O le yọri si igbe-aye ailagbara bii ara gige, aigbọran, ọpọlọ bibajẹ ati oju apa. Kokoro aarun meningococcal lo ma nfa eyiti o pin si orisirisi ipin. Eyiti o wopọ julọ ni A, B, C, W and Y. Awọn ikoko, ọmọde, agunbanirọ ati ọdọ ni ewu nla ti kokoro aarun meningocossal.**

Kokoro aarun meningococcal le fa kọọli (wiwu itẹnu ọpọlọ) ati kokoroinu ẹjẹ (nigbati kokoro aarun ba wọ inu ẹjẹ lati fa majele ẹjẹ). Awọn aarun mejeeji le gidigidi wọn si le pani, paapajulọ bi wọn ko ba tete mọ.

Awọn aarun kọọli ati septicaemia le wu sepsis jade. Sepsis jẹ eesi ajẹsara si eyikeyi aranmọ to le ti o si le pani o si le yọri si ẹya ara bibajẹ, ikuna ẹya ara ati iku.







## Kini idi ti mo fi nilo abẹrẹ ajẹsara?

Awọn agunbanirọ to ti dagba ati awọn ọdọ wa ni ewu giga lati ni kokoro aarun meningococcal, nitorinaa o nilo lati gba abẹrẹ ajẹsara nibayii lati daabobo ara rẹ. Eyi jẹ abẹrẹ ajẹsara o laabo to si munadoko eyiti o jẹ ara eto agbekalẹ agunbanirọ lati 2015. O ma ndin ewu awọn eniyan yooku to wa layika rẹ ku lati ni aarun naa. O ti le gba abẹrẹ ajẹsara MenC gẹgẹbi ọmọ ati ikoko sugbọn koni daabobo ọ tako awọn ẹgbẹ meningocossal yooku.

Abẹrẹ ajẹsara MenACWY yoo ṣe imugberu aabo rẹ tako MenC yoo si daabobo ọ ako ẹgbẹ meningococcal mẹta yooku (A, W ati Y). Abẹrẹ ajẹsara yii yoo daabobo ọ tako gbogbo irufẹ aarun meningococcal, bii MenB, yoo si tun ṣe pataki lati mọ awọn aami ati aami aarun.

## Njẹ mo nilo lati gba abẹrẹ ajẹsara MenACWY?

Rara, sugbọn ọna to dara julọ lati daabobo ara rẹ ni ki o gba abẹrẹ ajẹsara MenACWY. Iwọ, tabi obi/alagbatọ rẹ, nilo lati faramọ gbigba abẹrẹ ajẹsara naa. A o ma saba fun ọ ni abẹrẹ ajẹsara ni ile-ẹkọ ni saa ọdun 9 nigbati o ba pe ọmọ ọdun 13 si 14. Ma ṣe iyọnu bi o ba ti padanu abẹrẹ ajẹsara rẹ, o yege lati gba abẹrẹ ajẹsara MenACWY ọfẹẹ lai ile-ẹkọ nọọsi tabi ikọ gbigba abẹrẹ ajẹsara ti ile-ẹkọ bi o ba si wa ni ile-ẹkọ abi l'ọdọ GP rẹ, titi ọjọ ibi 25 rẹ. Awọn abẹrẹ ajẹsara MenACWY 3 lowa, a npe wọn ni MenQuadfi, Nimenrix ati MenVeo, o le ka awọn iwe pelebe Iwifun Alaisan nibi:

MenQuadfi: **www.medicines.org.uk/emc/product/12818/pil**

Nimenrix: **www.medicines.org.uk/emc/product/4118/pil**

MenVeo: **www.medicines.org.uk/emc/product/2939/pil**

## Njẹ abẹrẹ ajẹsara ma npani lara?

Kosi ẹniti o fẹran abẹ́rẹ́, sùgbọ́n o yara kiakia. Àwọn abẹ́rẹ́ ti alo keere o si yẹ ki o ni imọlara inira kekere. Bi ẹru ba nba ọ díẹ̀ nipa gbigba abẹ́rẹ́, sọ fu nọ́ọ̀sì tabi dokita sáájú ki o to gbaa.

## Awọn aami ati aami aarun

**Tẹlẹtẹlẹ aarun meningococcal le dabi iru ọfinkin to buru gidigidi. Sugbọn ẹniti o ba ranmọ yoo saaba ṣe aisan gidigidi laarin wakati perete. Itọju ni kiakia le daabobo ẹmi rẹ nitorinaa o ṣe koko lati mọ awọn koko aami ati aami aarun kọọkan.**

Ori fifọ lile

Ọrun gigan

Igbona giga

Giri/Idurosinsin

Itoogbe tabi inira lati ji

Iporuru ati/tabi ara hihun


Ọwọ ati Ẹsẹ tutu




Ọkan abi ọpọ awọn aami aarun wọnyi le waye wọn si le s’afihan lọnakọna ti yoo si dapọ mọ awọn aisan mejeeji. O ṣe pataki lati wa imọran iṣegun ni kiakia bi iwọ tabi ọrẹ kan ba ni aami aarun ifoya tabi ipo kan to nburu gidigidi.

**O ṣe pataki lati mọ awọn aami ati aami aarun kọọli ati kokoro inu ẹjẹ koda ti o ba ti gba abẹrẹ ajẹsara niwọnbi ọpọ idi to nfa awọn ipo yii lo wa.**

## n aami ati aami wọpọ wọnyi





Ol le ri awọn aami ati aami aarun kọọli ati kokoro inu ẹjẹ pẹlu awọn aworan ati fidio ni **www.meningitis.org** ati **www.meningitisnow.org**

*wo 'Ṣe ayẹwo gilasi' lẹyin iwe

## ‘Ṣe Ayẹwo gilasi’

Ẹnikan pẹlu kokoro inu ẹjẹ le ni àbàwôn kọọkan tabi ara susu nla pẹlu iba. Tobaya lori ara susu yọri si ara bibo pipọn ti kii parẹ labẹ ikimọlẹ. O le ṣe ayẹwo kan fun eyi nipa titẹ ẹgbẹ ife omi kan si oju ara susu naa. Bi o ba ni iba ati ara susu, ti ara susu naa kosi parẹ labẹ akimọlẹ, beere fun iranlọwọ iṣegun ni kiakia nipa pipe 999 tabi wa ẹnikan ti yoo gbe ọ lọ si ile-iwosan pajawiri to sunmọ ọ julọ. Maṣe duro de ara susu. O le jẹ aami pipẹ kan tabi ki o ma jade rara. Bi ẹnikan ba ṣe aisan ti o si n buru beere fun itọju iṣegun kiakia.

Lori awọ to dudu, yẹ inu ipenpeju tabi oke ẹnu wo nibiti oju rẹ ti le han kedere sii.





## Ǹjẹ́ àwọn ìdíjú kankan wà?

Ó wọ́pọ̀ láti ní ojú wúwú, pípọ́n tàbí rírọ̀ níbití o ti gba abẹ́rẹ́. O le ni ori fifọ bakanna tabi ṣe aisan diẹ sugbọn awọn aami aarun wọnyi gbọdọ parẹ lẹyin ọjọ kan tabi meji. Bi o ba ni ifoya nipa awọn aami aarun kankan beere fun imọran iṣegun nipasẹ NHS111 tabi GP rẹ bi o ṣe ma nṣe.



Bí o bá ní ìrírí èyíkèyí àwọn ìdíjú sí abẹ́rẹ́ àjẹsára náà tí o furasi, O le jábọ̀ èyí lórí ojú-ewé káàdì Yellow (Yellow Card) tàbí nípa pípe 0800 731 6789 (agogo 9 òwúrọ̀ si 5 ìrọ̀lẹ́ Ọjọ́ Ajé sí Ẹtì) tàbí nípa gbígba ápùù Yellow Card sílẹ̀ sórí ẹ̀rọ.

**Fun kọọli, awọn onitọrẹ-anu wọnyi npese iwifun, imọran ati iranlọwọ:**

**Ajọ Iwadii Kọọli**,
opo ipe ọfẹẹ 080 8800 3344 –
Ọjọ Aje si Ọjọ Ẹti, Agogo 9 owurọ si 5 irọlẹ

**Kọọli Nisisinyi**, opo ipe ọfẹẹ
0808 80 10 388 – Ọjọ Aje si Ọjọ Bọ Agogo 9 owurọ si 4 irọlẹ ati Ọjọ Ẹti Agogo 9 owurọ si 1 irọlẹ

Bi o ba ni ibeere kan tabi fẹ iwifun siwaju sii, ba dokita, ile-ẹkọ tabi nọọsi rẹ sọrọ ni ile abẹ dokita rẹ.

Ìwé pélébé yìí ni a ti pèsè láti ọwọ́ Àjọ Àbò Ìlera UK (UK Health Security Agency).

© Crown copyright 2024
1P 100K AUG 2023 (APS). Product code: YPMACWY1YO Yoruba.
UK Health Security Agency gateway number: 2024071.
O le bèèrè fún tàbí gba ìwé pélébé náà sórí ẹ̀rọ rẹ láti:
**www.healthpublications.gov.uk**, nipa pípe: 0300 123 1002 (Agogo 8 owurọ si 6 irọlẹ, Ọjọ aje si Ẹti). Àwọn ẹ̀dà ìwé pélébé yìí ní èdè Gẹ̀ẹ́sì wà ní àrọ́wọ́tó láti bèèrè fún.